**Owe**

Adię iba l'oko, iba l'atitan ṣe nkan. Imado iba ṣe bi ẹlẹde a ba'lu jẹ. Ẹru iba j'ọba, enia ko ba ti ku ọkan.

# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia ma jẹki t'enia sunwọn, t'eni ma sunwọn ko ni gbọ. Apa ọmọde ko ... ka igi Oṣe, ... ma doyika.

VOL. XII No 671. LAGOS, SATURDAY NOVEMBER 12, — NOVEMB... 18. 1960. KỌBỌ MEJI (2D)

# ENIA MERIN NFE JE OYE KANSOSO NI IGA OLUWA

Eko- Ijogboro fẹrẹ bẹ silẹ ni ọjọ ọsẹ (Sunday) ọjọ kẹfa oṣu yi nibi ipade gbogbo ẹbi ile Oye Oluwa ti nwọn ṣe ninu Iga Oluwa lori yiyan ọmọ Oye ti yio j'oye rọ'po ologbe Alhaji Amọdu Tijani, Oloye Oluwa.

Nigbati ẹsẹ gbogbo ẹbi oye Oluwa pe tan, ni Ọgbẹni Sufianu Oluwa ti o jẹ Olori ẹbi ile oye Oluwa fi orukọ Afapọ Oluwa siwaju wọn gẹgẹbi ẹniti yio j'oye na.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ẹbi da orukọ enia mẹta miran fun aye oye yi kanna. awọn mẹtọta ti nwọn daruko wọn na ni Ọgbẹni Ladipọ Oluwa, Adeniyi Oluwa, ati Kasumu Oluwa.

Nigbana ni ariwo ọrọ lile bẹrẹ ti agan fẹrẹ bẹ nigbati ohun nwọ'nu ohun, ti ariwo ngbojikan siwaju ati siwaju, ni nwọn ba ranṣẹ lọ pe awọn ọlọpa ti o wa da ẹrọ si fun wọn.

Irohin ti a tun ri gbọ ni wipe lẹhin gbogbo rogbodiyan na, Ọgbẹni R. A. Oluwa ti iṣe Alakoso ile iṣẹ burẹdi, (Adio Mainland Bakery) ti o ngbe No. 7, Oluwa Lane, ni Ijero, Ebute-Metta, ni nwọn yan

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## OLOTU IJOBA APAPOSE NILU IBADAN



Eyi ni aworan igb... Olotu Ijoba Apapọṣe ni alejo ni Liberty Stadium nilu Ibadan. Oloye Iyal'e Akintola, Alhaji Sir Abu-bakar, Oloye Akintola Olotu ijọba Iwọ-orun ati Ọgbẹni T. Ọ. S. Benson.

# ITAN IJERISI ORO BIBELI MIMO

Lati Owo J. Awojulugbo

Ce s r Ogosito, Tibarusi Sisa, Paileti, Erodu, ati awon pataki pataki be lati inu iwe itan. Won nran wa leti re inu aiye tia gbe bi Jesu si nijosi yen, inu aiye na ni awa papa si tun gbe titi di oni yi kosi iyato nibe ju ogbon oni lo.

Sisi Ogosito ti o wa lori oye nigbati abi Jesu si aiye je omo aburo Julius Sisa oun si ni eni akoko ti o de irufe ipo yen labe Ijoba ilu Rom. Oye yi ni a npe ni Emupro titi di aiye isinsinyi. O bo si ori oye yen lehin igbati o ti ba Maki Antoni ja ti o si segun re ninu ogun ti won ja ti a npe ni ogun Akitum ni odun kokanlelogbon ki a to bi Jesu (31 B.C.)

O si wa lori oye na titi di odun kerinla lehinti a bi Jesu tan (14 AB) Eniti o si dipo re lehinti o ti ku, ni a npe ni Tibarusi, on ni o tun je oye Emupro na on si wa lori oye titi di igba iku Jesu, ni odun kokandinlogbon lehin iku Jesu (29. A.D). Palesitaini si je eya ijoba ara Romu lasiko aiye Jesu, papa titi o fi di asiko yi ti a bere si nko iwe Majemu titun.

Awon Ju si ti bosi abe Ijoba Romu ni iwon odun ketale-logota sehin ki a to bi Jesu 63.B.C), nigbati okunrin alagbara kan ara Romu ti a npe ni Ogagun Pompe ti ja aja segun lori ile Judia, sugbon ki awon ara Romu to de, awon Romu ti de, awon Ju ti gbadun Ominira die sugbon ki se Ominira kikun o, eyi si je ati inu ofin Makabin wa.

Lehinti Romu ti segun Palesitian tan, omo Idumer okunrin ti a npe ni Antipa ni won fi je oye Gomina si ilu Galili, o si tun je alase lori gbogbo ilu Ju. On si ni Erodu ti o joba lasiko ti a bi Jesu. Siwaju ibi re abi Jesu ni odun karun (5.B.C) Erodu si ku (4BC) odun kerin siwaju ibi Jesu.

Lehin iku Erodu, o pin ijoba re ti o wa labe Romu fun awon omo re. Amu Akelo je Olori ilu Judia, ati Samaria. Erodu Antipasi si je Olori ile Galili ati Peria. Filipi si je Olori ile kekere kan nitosi omi adagun kan ni Galili ni iha Ariwa ilu Palesitaini.

Nigbati Josefu ati Meri pada lati Igibiti wa pelu omo na, Jesu Kirisiti, won yi ero won pada pe awon ko ni duro ni Judia mo gegebi won ti pinu tele, nitoripe Akelo ni Olori ile ibe.

Sugbon anu se ni pe awon ara Romu ni lati wa Akelo kuro lori oye na nitori isekise re, eyi si sele ninu odun kefa lehin iku Jesu (6 AD).

(Wo yoku loju ewe keje)

## Nwon Fi Abuku Kan Akowe Asoju Ile Ghana

AMERICA - Ogbeni W. M. Q. Halm, ti ise As'oju pataki fun ilu Ghana ni America l'o so wipe olopa fi abuku kan akowe Asoju ile Ghana nilu Atlanta, Georgia, nigbati o nworan ibo ti nwon ndi.

O so wipe aose eto lati fi oro na han Ijoba America. Eniti nwon fi abuku na kan ni Ogbeni H. V. H. Sekyi, akowe keji fun As'oju ile Ghana nilu Washington.

## Ole Ji Basikulu Olopa Gbe

Ilesha- Ogbeni [illegible] ni a gbo wipe o kan olopa ibile kan lese ni imu, o si ji basikulu olopa na gbe lo.

Ogbeni Isaac A[illegible]d[illegible] olopa ibile ti o so wipe on ti de ile-[illegible]

(Wo yoku loju ewe keji)

# IPADE AWON OLUKO NILU OYINBO



Alhaji Abdulmaliki ti ise As'oju agba fun gbogbo ile Nigeria ni a nwo [illegible] yi ti o mba awon oluko agba ye soro ninu ipade won ti nwon [illegible] Sosi Westminster nilu London laipe yi.

Eniti o wa lowo osi patapata ni Emi-ola Iyafin Vijaya Lakshmi iyawo As'oju agba ile India, ati Oloia Oloye na Earl of Perth, Alabojuto awon ilu okere ati Ogbeni N. Macpherson akowe Alabojuto ilu Scotland.

## Abiyamo Ji Aso Adire Gbe

ABẸOKUTA - Obinrin adelebọ kan ti o ntọ ọmọ ekee lọwọ ti nwọn npe orukọ rẹ ni Afusatu Adunni ti o ngbe adugbo Ikija ni o bu sẹkun ni kotu nigbati adajọ sọ pe o jẹbi ẹsun ole ti nwọn fi sun.

Alafisun na ni Afusatu Agbekẹ o sọ pe ni ọjọ 14/10/60, on ko aṣọ Adirẹ mẹsan sinu iyara on nigbati on jade lọ s'ode, Ọgbẹni Bisiyu Iṣọla ti o nṣe igbọnsẹ ninu igbo to wa nitosi ile awọn ni o ri ọdaran yi nigbati o gba ọna ẹhinkule wọ iyara on, o si ṣ'akiyesi pe o ṣe jamba kan nibẹ f'o ba sọ fun awọn ara ile ẹlomiran si ri obinrin na ti o sare gba iwaju ile jade ni nwọn ba ranṣẹ pe on.

Nigbati on pada de ni aṣọ mẹsan di awati ninu iyara lẹsẹkẹsẹ ni awọn wa ọdaran na lọ sile rẹ. agbare-gbabọ, nwọn lọ ri awọn aṣọ na nile Alaro ti o ko wọn fun lati pa laro. Ibẹ ni nwọn ti lọ pe ọlọpa ti o mu. Gbogbo aropo owo awọn aṣọ na jẹ ponun mẹta ati ṣile mẹsan. (£3. 9s. 0d).

Adajọ sọ fun ọdaran na wipe bi ko si ti ọmọ ti o ntọ lọwọ, ẹwọn ni on iba ju si, ṣugbọn on fi eyi ṣe ikilọ fun ki o lọ so agbaja modi fun oṣu mẹ lori adọta ... Eyini ni wipe bi o ba ... de Kotu yio san a... ... ponun tabi ki o lọ ... oṣu mẹfa.

## DEREBA MOTO F'ARAKORIN

ABẸOKUTA - Ọgbẹni Buraimọ Kayọde ti o ngbe NO 8 Glover Street, l'Eko ni nwọn mu de iwaju adajọ Kotu Abẹokuta ni ọjọ kejidil ọgbọn oṣu October 1960, fun ẹsun wipe o nwa Moto nla akeru laiko ni iwe Ẹri fun eto ifidoṣo (Insurance Certificate) ati iwe aṣẹ Moto (Vehicle Licence).

Adajọ sa konko ponun marun-lelad ta tab' ẹwọn oṣu mẹfa mọ lara.

Ẹjọ miran ti o tun ni, ni ti ẹsun pe o fi moto akeru ko ero, ko tun ni Iwe ẹri pe Moto rẹ dara loju ọna, ni Ewekoro, iwọn ogoji ibuso si Abẹokuta, adajọ yẹ ẹjọ na si ọjọ 29/11/60.

Ẹnyin Awam to, ẹsọ di ọwọ nyin o.

## Alabẹde Di Ijoye Oganla

ABẸOKUTA - Ọgbẹni Jimọ Ọladipọ Alabẹde ni nwọn fi j'oye Oganla ilu Eruwọn ni Abẹokuta ninu ile Oloye Salami Ọlọpade, Balogun Erunwọn, (oye awọn ologun ni oye na).

Balogun Erunwọn l'o ṣeto oye na pẹlu awọn Ijoye Ologun, Oloye Ajibọla, ti ṣe Aṣipa ni o fi ewe oye le Oloye titun na lori loju awọn ọpọ enia l'ọkunrin ati l'obinrin nilu Erunwọn.

Lẹhin ifi'jẹye ni awọn enia ati awọn Ijoye Ologun tẹle Oloye titun na lẹhin lọ si ile rẹ ni Agbọle Ẹdun Adila ni Eruwọn, nibẹ ni nwọn gbe ya aworan ajọya fun iranti ọjọ ti nwọn fi Ọgbẹni Jimọ Oladipọ Alabẹde j'oye. Lẹhinna ni ariya bẹrẹ pẹlu jijẹ ati mimu, orişirisi ilu ati ijo ajogbadun titi di oganjọ oru ọjọ na.

Awọn ti a le darukọ nina ọpọlọpọ iwọn enia ti o wa nibi oye ni ti S. Oyegunle

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

## Otito Ni Tabi Iro

MOSCOW. Lati ilu Moscow ni agbaye ina irohin ti kan wa wipe Ọgbẹni Nikita Krushchev ti iṣe akọni Olotu ijọba ilẹ Russia ni nwọn ti rọ loye, ti nwọn si fi Ọgbẹni Georgi Malenkov ti o tijẹ Olotu ijọba ri rọpo rẹ. Irohin yi tan kalẹ nilu Vienna ṣugbọn ko si idamu kankan ninu olu ilu Russia, ko si apẹrẹ iyatọ rara ni ile Ọba ti ni Kremlin.

Ọpọlọpọ ohun oṣọ ni nwọn ti ṣe si ilu lati fi ṣe ajoyọ ọtẹ ọdun 1917. Aworan Ọgbẹni Krushchev pẹlu awọn ohun ti nwọn fi ṣe ilu na l'ọṣọ.

Ko si ẹniti o tilẹ mọ ibiti Ọgbẹni Malenkov ti nwọn wi na wa nisisiyi. Ọgbẹni Krushchev ni a gbọ wipe o ba Ọgbẹni Frank Cousin sọrọ ninu oṣu to koja wipe bi o ba di ọjọ kẹdọgbọn oṣu October, on yio dakan lọ si Okun-dudu, (Black Sea) lati lọ ri Ọgbẹni Anastas Mikoyan ti iṣe Igbakeji Olotu ijọba nibi ti o gbe nṣe isinmi rẹ.




*Always ask for*
**'DE FACTO'**
*the bread with the appetising flavour*

# ELETI - OFE

ANJUWON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28 Kosoko Street, Lagos "ELETI OFE, LAGOS
P. O. Box [illegible] Phone 23330

VOL. XII NO 671. SATURDAY NOV. 12, NOV. 18, 1960


# IWA RERE L'ESO ENIA

Awọn Yoruba mọni-mọni ni nwọn ma npa l'owe wipe "Iwa rere l'ẹsọ enia", eyi kii ṣe owe lasan. O jẹ akanṣe ọrọ pataki ti awa ọmọ enia nilati fi ṣe ẹkọ kọ ki a si fi ṣe iwa hu, ki a le mọ adun ti o wa ninu ọrọ wura na. Nitoripe itọwo ni a fi nmọ ọbẹ ti o ni iyọ.

Ẹjẹ ki afi iwa wa ati iṣe wa han gẹgẹbi ọmọ ilẹ Nigeria ti o ṣẹṣẹ di ọkan ninu ọmọ titun Orilẹ-ede agbaiye, ninu otitọ ati ododo ṣiṣe ninu ile wa, nibi iṣẹ wa, ninu isọrọ ati ihuwa wa si aladugbo wa, nipa bẹ, ao fi han pe omi titun wọ odo o si yẹ ki ẹja titun wọ inu odo na.

Iwa jibiti iwa k'ẹnimani, iwa abinu-ẹni ti ko kan aimọ iwa hu, asiko na to ti a nilati fi ara wa ati ilu wa han bi Orilẹ-ede ti o pe, ti o si to lati da duro fun'rarẹ gẹgẹbi okiki rere wa ti kan kakiri agbaiye.

Ẹjẹ ki a huwa rere.

# NATHAN MARSH J'OYE IWAREFA

ABEOKUTA — Alaiyeluwa, Sir Ladapọ Ademọla, Keji Ọba ilu Abẹokuta, ni o fi Ọgbẹni Ọladisun Nathan Marsh, B.L. LL.B. (Leeds) j'oye Iwarẹfa, oye Kemọ Ake, (Agba oye ni oye na jẹ). Ọgbẹni Nathan Marsh yi wa fun ajọyọ Ominira ilẹ Nigeria lati ilu Oyinbo ti o fi ṣe ibugbe.

Oloye titun na jẹ ọmọ Ẹgba, o si jẹ ọkan ninu awọn arọmọdọmọ Ologbe Daddy Henry Robbin, (ọba ninu Oniṣowo Ake) laiye rere ijọun. O si tun jẹ arakunrin Olori Layide Marsh ti iṣe iyawo Ọba Samuel Adeṣina, Ọlilubu Keji, Olubara, ti ilu Ibara, Abẹokuta.

Gbogbo eto ifijoye na, Oloye Apena Ake ni o ṣe pẹlu awọn Ijoye, Oloye Iyafin Labọde Mọsade Ake ni o fi ewe oye le Oloye titun na lori. Lẹhinna ni Oloye titun na ba wọn y[illegible] awọn Oloye ẹgbẹ rẹ, ki nwọn to lọ ayẹyẹ na lọ si Afin Olubara nibiti nwọn gbe ṣe ariya pẹlu ijẹ ati mimu titi di alẹ.

Kabiyesi Ọba Alaiye Ade a pẹ lori, Bata a pọlẹṣẹ o, Oye na a mọri fun Oloye titun na.

NO. 157.

# Rememberance Day Sunday 13th November, 1960

A service will be held in the Cathedral Church of Christ on Sunday the 13th November, 1960, at 10.30 a.m.

2. The Commander 2 Brigade representing the General Officer Commanding the Royal Nigerian Army, the Inspector-General of Police and the Commodore Commanding the Royal Nigeria Navy will arrive at the West Door of the Cathedral at 10.25 a.m. and will be met by the Provost.

3. His Excellency the Governor-General will arrive at the West Door of the Cathedral at 10.28 a.m. where he will be met by the Bishop of Lagos.

4. Blocks of seats will be reserved for which tickets will be issued. Tickets for seats reserved for Ex-Servicemen can be obtained from the Secretary, N. E. W. A., 20 Campbell Street.

A number of seats in the Cathedral will be available to the public. Tickets can be obtained from the Ministry of Lagos Affairs.

5. Copies of the Order of Service will be distributed at the Cathedral.

6. Persons attending the service should be in their seats by 10.15 a.m. Uniform, Medals and Decorations should be worn by those entitled to do so.

7. At 10.45 a.m. a Guard of Honour from the 3rd Battalion, Queen's Own Nigeria Regiment and the Royal Nigerian Navy will be mounted at the War Memorial, Idunmota.

8. At 11.00 a.m. two guns will be fired. All noise should then cease until two minutes after the hour when one gun will be fired. In the Cathedral, buglers of the Nigeria Police will sound the last Post and the Reveille immediately after the Silence.

9. At the close of the Service His Excellency the Governor-General followed by the Commander, 2 Brigade representing the General Officer Commanding the Royal Nigerian Army, the Inspector-General of Police, the Commodore Commanding the Royal Nigeria Navy and the Secretary, N. E. W. A., will leave the Cathedral by the West Door and will drive to the War Memorial by way of the Marina, Balogun and Ereko Streets. On arrival at approximately 11.25 a.m. they will be met by the Minister of Internal Affairs, the Deputy Commander, 2 Brigade and His Highness the Oba of Lagos. Wreaths will be laid by:-

His Excellency the Governor-General.
The Minister of Internal Affairs (on behalf of the Council of Ministers).
The Commander, 2 Brigade, the Royal Nigerian Army
The Inspector-General of Police.
The Commodore Commanding the Royal Nigerian Navy
His Highness Oba Adele II
The Secretary of the Nigerian Ex-Servicemen's Welfare Association

A representative of Nigerian Ex-Servicemen.

10. A March past of Ex-Servimen, led by the Band of the Queen's Own Nigerian Regiment, will then follow; His Excellency the Governor General will take the salute.

11. His Excellency will leave Idumota by way of Victoria Street and Tinubu Square. After these departures those members of the public who wish to lay wreaths may do so.

12. The Cathedral Service and the laying of wreaths will be broadcast by the Nigerian Broadcasting Corporation.

13. The War Memorial will be flood-lit on the nights of 12th, 13th and 14th November.

D. J. BROWN
for Ag. Permanent Secretary,
Ministry of Lagos Affairs.

## Olopa Mu Awon Oga Ile Tete (Pools)

EKO— Enia meji-dilogun, okunrin ati obinrin, Yoruba, Kora (Serians Lebanese) ni awon olopa ko de iwaju adajo ni ona meji nilu Eko, ati Kotu Yaba ni Ebute Metta ni ojo Monday ojo keje osu yi, fun esun wipe nwon si ile Tete lai gbawe ase.

Nigbati afisun ti pa poju ni Sobu olopa ni nwon fi lo se ofintoto iwadi wo, ki nwon to ri awon enia na ko.

Ni Kotu ti Yaba, awon meji gba pe awon jebi esun na, adajo se idajo ogun ponun (£20) ni sisan tabi ewon osu meji fun enikokan, awon enia meje ti o ku so pe awon ko jebi. Adajo ye riro ejo won si November, 23, sugbon ki nwon fi aradota ponun duro fun enikokan ati Oniduro won bakanna.

Awon isi keji ti Kotu Eko, ni awon mesesan so pe awon ko jebi. Adajo ye riro ejo won si November, 25, nwon si gba iduro fun won bakanna.

## Okunrin Kan Te Iwe Tete

IBADAN—Clement Akinlolu Obisesan, ti nwon mba rojo lori esun mejila fun iwe yiyi pada ati ole jija, ni o tun so pe on ko jebi lori esun marun miran pe o tewe tete o si ta won gba owo.

Awon olopa so pe Akinlolu te iwe Tete 988 larin osu December odun tokoja si osu October ti odun yi, laiko ni ase lati se be o si ti ta 58 ninu awon iwe na ti o ti gba £44 : 6 : 6.

Adajo ye riro ejo re si ojo kedogun osu December o si gba iduro fun lori igba ponun (£200) ati Oniduro lori iye owo kanna.

### IPONJU KO DI IRE OLORUN LOWO

LEOPOLDVILLE - Iyawo Olotu ijoba Congo ti nwon ti fi ote le jade nilu, Ogbeni Patrice Lumumba ni o bimo obinrin sinu ile re ti o wa leti odo, nibiti nwon gbe salo fi ara pamo si.

Lati ojo kerinla osu September ni Ogagun Mobutu ti se mo ibe ti ko le jade.

A ki Lumumba ku ewu omo titun alejo aiye, "Ibinu enia ko le da ise Oluwa duro."

## Omo Ile Nigeria Nilu Oyinbo



Aworan ti a nwo yi niti Ogbeni L. G. Harry omo ilu Abonema nile Ibo Nigeria, ti o ti sise nile ise Olotu ijoba l'Eko, o si ti wa nile Oke-oya nile ise Alaboiuto eko iwe nilu Kaduna.

Nigbati o lo ko ise Oko ofurufu nile Gesi nilu Oyinbo. Nisisiyi, Ogbeni Harry nko bi a ti nsise ni ibudo Oko ofurufu.

## Akowe Ile Iwosan Jebi Esun Ole

EKO - Ogbeni Johnny Akaere ti o nsise ni ile ise Onisegun ijoba ti nwon f... esun wipe o ji owo ti o le ni egberun ponun ni o gba niwaju adajo pe on jebi esun na.

Eniti nwon mu pelu re ni Babatunde Ojomu ti nwon jijo mise nibikanna, eleyini so wipe on ko jebi, adajo wipe on ko ni se idajo fun Akaere titi ti on ma fi gbo oro ejo ti Ojomu.

Adajo ye ejo na si igba miran.

## Ewon Odun Meta Fun Elewe Taba Igbo

IBADAN - Ogbeni Sabitu Aremu ti ko ju omo odun medogbon lo ni o ti w'ewon lemejo, Kotu Ibadan tun ja si ewon ekesan fun esun wipe o ni Ewetaba ti nwon npe ni Igbo lowo. (India Hemp).

Eleyi ti di Apele-on si obo - Ewon odun meta ni adajo ju si.

OKU'JA WOLU

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ENITI O NRA OJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI SE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONISOWO LE SE TI OJA RE YIO FI MA TA BI ISU AKARA GBIGBONA

E Polowo Oja Yin

Sinnu Iwe Irohin

ELETI-OFE

## Baba Agbe Kan Fi Jibiti Gb'owo

ABEOKUTA - Okunrin agbe kan ti o ns'se agbe roko, o fere to eni arọta ọdun ni ojo ori re, si Olopa mu wa si aju adajo Kotu fun esun wipe o fi jibiti gba owo ponun merin ati sile mejo lowo enia merin ni abule won. Abule Apolo nitosi Abalabi, ni agbegbe Egba Ifo, oruko re nje Sanni Oguntoyinbo ti o pe ara re ni asoju Wole-wole, o so pe on ko jebi.

Bi oro na ti lo nsyi: Ni asale ojo ketadinlogun osu August ti odun yi nigbati awon mererin ti ibi ise won de si Abule ni awon ara ile so fun won wipe Sanni Oguntoyinbo pelu Wole-wole kan ti wa wo ile won losan atipe Wole-wole na si ko oruko won sinu iwe re fun ohun egbin to ri ninu ile awon mererin. Awon alrfisun na ni Gbadamosi Yesufu Ogunsare, Daniel Ogunrombi ti Ijo Aladura.

Lateye meji, awon mererin lo ba Ogbeni Sanni Oguntoyinbo o si gba sile mejilelogun (22/-) lowo enikokan lati ba won fifun Wole-wole ki o ma ko oruko won lejo. Apapo gbogbo owo ti o ba jẹ £4 ati s:0 Sugbon iyalenu ni o je fun won nigbati awon fun won ni iwe ipejo lehin osu meta ti nkan yi ti sele fun esun pe awon ri idoti ninu ile awon ni ojo ketadinlogun osu Agust. Kotu Ifo si a konko ponun meji-meji mo enikokan won lara fun sisan si apo ijoba.

Lehinti nwon san'wo na tan ni nwon lo fi oro na han awon Olopa, ni nwon ba lo ra cdaran ne mu.

Nigbati adajo bere lowo re pe o jebi tabi ko jebi, o so wipe on ko jebi, adajo ye riro ojo na si ojo keje osu Nov, 1960.

Bi a ba ti tun gbo si ao ma fi to yin leti.

## Awon Janduku Da Igbimo Ru

OFFA-- Irohin ti a gbo ni ojo Satide ti igbimo ibile ilu offa se ipade akoko eyiti awon egbe Afenifere (A. G.) je asiwaju ninu igbimo na, awon janduku enia wa da igbimo na ru pelu kumo ati kondo depo ti enia merin fi di gbigbe lo si ile Iwosan (Hospital) nipo ese kan ati ese kan orun.

Rogbodiyan na bere nigbati ohun awonu ohun ido'ako larin omo egbe Action Group ati N.P.C. ninu igbimo.

Nigbati igbimo jade ni awon janduku ko kumo ati ada ti awon egbe ti ko si ninu ti won.

ALABEDE DI IJOYE
(O bere loju ewe keta)

Balogun Ijesa, A.K. Odenike Jagunna awon Imale Oko, Ogbeni B.O. Eden, L. A. O. Sanni, Lasisi, Amos, Sodunke Alimi Gbomo, Murana Ajadi Sikiru Olun, S.T. Adeneye ati awon opo enia ti a kole daruko tan.

Oye na a mori o.

## OMOBA ALEXANDRA NILU BIDA



Aworan oke yi ni eyiti awon ya nigbati Omoba Alexandra ti o wa s'oju fun Alaiyeluwa Oba Obinrin ilu Oyinbo Gesi nigba ayeye Ominira ile Nigeria nilu ile Oke-Oya wa ninu oja ilu Bida ile Ariwa.

Omoba na ni o nye awon ileke wo ti Olagbimo ibile Madaki ilu Bida nse ogbufo fun u.

# Dokita Nigeria Nilu Oyinbo



Dokita Olu Seriki ti o nșișę ni Ile iwosan ilu Shagamu nilę Ijębu Ręmọ Nigeria, ni a nwo ninu aworan yi ti Ọgbęni David Jenkinson ti ile ișę British Conncil nki k'abọ nigbati o nsọ kalę ninu ọkọ Apapa nilu Liverpool.

Dokita Seriki yi ni awọn igbimọ agbaiye fun ni aye ękọ-ọfę fun itọju awọn ọmọ wẹrę nilu Oyinbo fun ọdun meji.

Awọn enia bi adọsan ni Ijọba ilu Oyinbo yọnda ękọ ọfę fun gęgębi eto awọn Igbimọ agbaiye (Common-wealth) nwọn si ti npesę silu Oyinbo nisisiyi.

## Asinwin To Ko Ohun Ija Dani W'ewon

ILESHA-Ọkunrin așiwere kan ni ọlọpa mu wa siwaju adajọ Kotu ibilę nilu Ilesha, fun ęsun wipe o nko nkan ija bi kumọ, ada ati ọbẹ rin kakiri larin ilu lati fi da idagiri silę.

Ọkunrin așinwin na ni orukọrę njẹ Gabriel Aduroja, adajọ ju s'ęwọn ọdun męta, o sọ wipe on ni ireti pe ori rę yio ti wale gęgębi ti enia ki o to jade ninu ęwọn.

## Egbaji Omo Egbe Mbe Ni Inu Tubu

MAKURDI— Ninu ipade apero nla ti ęgbę Afẹnifẹre șe pęlu UMBC nilu Makurdi ni Ọgbęni Patrick Dokotri, akọwe gbogbogbo ęgbę UMBC ti sọ ninu ọrọ rę wipe ęgbaji ọmọ ęgbę UMBC dapọmọ Action Group ni nwọn mbę lọgba ęwọn.

Ọgbęni Dokotri sọ wipe lori ęsun așe ipade lai gbawe așę tabi nwọn ri ohun an.i ęgbę lara wọn ni nwọn șe ju wọn s'ęwọn. Awọn meji ninu awọn ti nwọn ju s'ęwọn jẹ ọlugbimọ ninu ile igbimọ Așofin.

Irufę iwa Ika bawọnyi ti da aifaiyabalę silę, adębin... rę si ti ba ęgbę N. P. C.

Or... yi jęde ninu ipade ọdọdun karun ti o sęsę pari nilu Makurdi.

## Itan Ijerisi Oro Bibeli Mimo

(O bẹrẹ loju keji)

Lęhin eleyi ni Romu bęrę si nran awọn Oloye pataki-pataki wa lati șe alakoso lori ilę Judia. Ikan ninu ninu awọn Oloye wọnyi ni Pọntin paileti ti o wa lori aga nigbati akan Jesu m gi ni ọdun kọkandilọgbọn, lęhin iku Jesu (29 A.D). Erọdu Antipasi si wa lori oye ni ilu Galili ni gbati akan Jesu mọgi. On ni Paileti fi Jesu ranșę si nigbati o gbọ pe Jesu papa ara Galili ni ișe. On na si ni Erodu ti o pașẹ pe kia ...ẹ John Baptist lori ...u Tubu.

Eo tun ...a gọọ, nipa awọn ęgbę ti a npe ni Zealot.

## Enia Meta Pin Ewon Odun Mesan

Eko- Awọn Onișowo męta, Joachim Ezeoka, Kalu Nnana ati O. Ogugua ni adajọ șa konko ęwọn ọdun męta-męta mọ lara fun ęsun ole jija.

Awọn ọlọpa sọ wipe awọn onișowo męta ji apoti bata meji gbe ti apapọ owo rę jẹ arunle-logoje pọun (£145) ęru ile ișę ijọba Ebute (Nigerian Ports Authority).

"Elejọ ki i mọ ęjọ rę lębi, ki o pe ni ikunlę ni awọn ọdaran fi ęjọ wọn șe, awọn męta gba wipe awọn jębi ęsun na.

## OLE JI BASIKULU OLOPA

(O bere l ju ewe keji)

(Post Office) lati lọ șe eto ati ra Otitę (Stamp) ti on si gbe kękę-ologere on ti ... ilai. ni ọkunrin kan ... ju sose ... fi ji basikulu ... gbe sa) bamoa....

## DOKITA AZIKIWE YIO J'OYE GOMINA AGBA

EKO — Ni ọjọ marun oni, ọjọ Alaruba, (Wednesday) ti iṣe ọjọ kerindilogun oṣu November yi, ni awọn yio fi Dokita Nnamdi Azikiwe mu ibura fun oye Gomina Gbogbo-gbo, Alaṣẹ pataki ati Aṣ'oju Alaiyeluwa Oba ilu Gẹsi nilẹ Nigeria igbimọ ilu Kamarun lẹ p'ohunda nilu Oyinbo ti nwọn lọ fun ọrọ eto ilu.

Ọgbẹni Endeley ti iṣe Olori Alatako ni a gbọ wipe yio bere fun ominira ilu Kamarun lati duro gẹdẹ,laiko fi ara mọ ilu kankan bi Oloruijọba Kamarun ba gba bẹ, ki o ma fi ara mọ Kamarun ti Ariwa ti o ti da duro.

K'aṣimawo bi oruko ọmọ ọlọmọ.



Adajọ Agba Sir Adetokunboh Ademọla ni yio ṣe ibura na fun Dokita Azikiwe ni gbangba Ọdan.

## New Oluwa Elected

On Sunday the 6th inst the entire Family of Oluwa Chieftaincy met, and unanimously appoint Mr. R.A. Oluwa of No. 7 Oluwa Lane Ijero Ebute-metta Managing-Proprietor of Adio - Mainland Bakery to succeed late Oluwa The Chief Elect will soon be presented to Oba Adele II.

The Chief Elect is now occupying the Iga Oluwa.

## Enia Merin Fe J'oye

(O bẹrẹ loju ewe kini)

lati jẹ oye rọ'po ologbe Oloye Oluwa.

A si gbọ pe laipẹ yi ni awọn ọmọlẹbi ile oye yio mu oloye titun ti nwọn yan na lọ fi han Alaiyeluwa Adele Keji, Oba Eko.

Oloye titun ti nwọn yan na nio wa ninu Iga Oye Oluwa nisisiyi, ibẹ si ni yio ma gbe titi ti nwọn a fi mu lọ siwaju Ọba ni Iga Idunganran l'Eko.

## Alatako Igbimo Ilu Kamarun le P'ohunda.

SOUTHERN CAMEROON— Irohin ti a ti gbọ lati ilu Kamarun ni wipe Olori ijọ Alatako inu


# L. E. D. B.

## FLOWER SHOW

### TODAY

AT

## FUJAH ROAD

SURU - LERE
4. 30 p. m




PRIZE-GIVING PRESENTATION
BY
**LADY ROBERTSON**


## Nwon Ko Omo Ibeji Sinu Igbo

LOKPA UKWU - A gbọ wipe nwọn gbe awọn ọmọ ibeji meji ju sinu igbo nilu Lokpa Ukwu nj agbegbe ilu Okigwi.

Irohin ti awọn ọlọpa gbọ nilu Enugu ni wipe awọn ọmọ ti o nlọ si ilewe ni nwọn ngbọ igbe ọmọ ikoko ninu igbo, nigbati nwọn de ilewe ni nwọn sọ fun Olukọ wọn, ẹniti o pada sọ fun awọn ọlọpa. Nwọn ri awọn ọmọ na gbe ni aaye.

Awọn Ọlọpa ti pe ọkunrin kan ati iyawo rẹ fun ibere lọwọ wọn gẹgẹbi nwọn ti ni ero pe awọn ni obi awọn ọmọ ibeji na.

Awọn Ibo ko ni ṣiṣọ ninu ọrọ pe "Ako gbọdọ bi ọmọ ibeji yi"?


**HAPPINESS SUPREME!**




"Ma gives me "BANWO" and so, I'm strong robust and healthy."


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, P.O. Box 467, Lagos. Phone 2337)